To the Chief Secretary to Government

# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. II. No. 76. SATURDAY, DEC. 22, 1923. Fourpence.


## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

---

Ọgbẹni **DURO THOMAS**

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Măse leti ita Faji, l'Eko.

---

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

***J. F. SICK*** ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l'eti *Glover Memorial Hall, (Customs Street,)* EKO.






Awọn Oyinbo Onişowo yi nranşẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1–4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ransẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nṣe orişirişi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranşẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja abọmafọ ati orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja *Excelsior* " ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun elo fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorisirisi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onisowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ o.

**B. O. Joseph**

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

Cotton.

Sundries.

Hardware.

Provisions.

27, Koseh Street, Lagos.

Cable Address:—
"Steinafrik" HAMBURG.

E. H. STEIN & Co.

HAMBURG, Neurwall 16/18.
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

**ALL INDENTS EXECUTED.**
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
Broad Street, & Portonovo Market Store.

ẸNIKẸJI.

Aṣọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

# OPO OJA MBE

NI ILE EGBOGI NLA TI FILIPI TI A NPE NI

## *Phillips' Medicine Store*

ni Ajẹlẹ, Ita Faji, Ita Balogun, ati ni Ebute Mẹta (17 Ibadan Street.)

A nta ọpọlọpọ Egbogi iyebiye eyiti awọn enia ko mọ tẹlẹ ri, ati awọn miran ti nwọ jẹ egbogi titun ni ọpọ lati ba jẹ ki awọn onibara wa mọ wọn.

Origi awọn Egbogi na pọ ju eyiti a le ma kọ silẹ ninu iwe yi, bẹni ẹdin owo ori wọn si pọ to, sa wa wo wọn.

Lẹhin *Christmas* (Keresimesi) owo awọn Egbogi na yio pada bọ si ipo wọn Nitorina, ma jafara.

Ọpọlọpọ Egbogi miran ti o ti mọ ni ô si ri ra ni ọpọ pẹlu.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices:* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/-• | 13/- | 14/- |
| Oșu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oșu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranșẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

A BỌ O, ABỌSẸDE.

Ku ewu ni a ki Iya-afin Mrs. Adedapọ Kayọde ti Idunșagbe l'Eko, fun ọmọ'bin-rin kan Aji-șe-fin-ni to fi ta ọkọ rẹ *Lawyer* Kayọde lọrẹ ni *Sunday* to kọja. Ki Baba ki o wo ju wa lọ—Amin. A ș'abere Tokunbọ ọrẹ wa; alafia k'o wà bi? Ki Baba jẹ ki a ri nyin gbe șere k'alẹ. Așẹ!

ORI ỌWA A GBE Ẹ O, ȘAPARA ỌMỌ LORO AGBOGBORIGUN.
O YẸ Ẹ O!

Kasinkan ni ẹyẹ ti awọn ọmọ Ẹgbẹ Ekitiparapọ șefun Dokita Oguntọla Șapara ni *Saturday* ọjọ kẹjọ oșu yi ni Ita Balogun fun ọla ti Ọba *King* George da nipa oye I.S.O. ti Alaiye-luwa fi fun u nitori ișẹ Ișegun rẹ to larinrin jakejado gbogbo aiye. Nșe ni orin npe orin ranșẹ lọjọ yi, awọn ọmọ Ẹgbẹ si pe bibà, a si fi ohun ipanu ati nkan mimu su ẹnikẹni nibẹ, a ka Iwe Iyẹsi ti awọn Ẹgbẹ na wa fi yẹsi nitori ọla yi; Ọgbẹni *Lawyer* Alaka Cole olohun-iyọ ninu ede Gẹsi, lo ka ti Oyinbo Iwe Iyẹsi na; Ọgbẹni J. Roșiji Turton Akọwe Atata ninu Ișẹ Ọba, lo ka ti Yoruba rẹ. Orukọ awọn Ijinmi to fi ọwọ si'we na leyi:—

Ọbasa ara Ikija
J. H. Doherty,
C. da Rocha,
Peter J. C. Thomas,
Alfred Ọșodi,
C. C. Adeniyi Jones
A. Oyejọla,
J. T. Nelson Cole,
G. D. Agbebi,
O. H. Williams,
Dan Șașẹgbọn,
J. Bagan Benjamin,
L. A. Cardoso,
E. J. Alex Taylor,
Mrs. Abimbọla Gibson,
Mrs. Lydia Luke.

Oloye Arapatẹ ni Ọwa Iku baba yèyé, Alașẹ ekeji orișa, ran wa șoju rẹ ninu Ipade yi; a si mu Ọpa Ọba na wa pẹlu. A gbọ pe Ọgbẹni wa Candido da Rocha ọmọ "Odùbúlẹ̀ta," A r'owo șe fuja, lo șe inawo ọkọ ti awọn enia ti Ọwa ran wa wọ t'alọ-t'abọ.

Ẹ ku așeyẹ ọjọ o, bẹbẹ ni ka ma ri.

ẸNYIN ỌMỌ WO-NPA-PA.
ỌMỌ FITI-NA-TI, Ẹ NTẸ OFIN LETI.

A gbọ pe gẹgẹ bi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ndari bọ wa'le rẹ lati *Jimoh* ọsẹ to kọja ni awọn ọgọrọ ọmọ kan t'ọkọnrin t'obinrin ni opopo Ẹhin-ọgba si nho le pe O......... a tilẹ gbọ pe bi ko si ti awọn ọlọpa diẹ to wa lapa ibẹ ni, awọn ọmọ na iba rọlu laișe-lairo: o da ni lọju pe ko si ẹnikan to jẹ ran awọn ọmọ abilisi yi ni'șẹ ti nwọn jẹ nijọ na; a si fẹ ki nwọn șe mẹlọ-mẹlọ ki nwọn ma ba da si awọn agba ilu lọrun njẹ bi o lọ di pẹ ntuka nkọ, ti ọwọ Kester, Kiniun Kotu tẹ wọn, nșe ni nwọn iba lágun de ori ekanna; mẹlọ-mẹlọ dọwọ nyin o, ẹnyin ọmọ wọnyi. Ko si ẹniti o ran nyin ni'șẹ!

Ẹ mașe fi ti nyin kọ awọn ẹlomiran lọrun, ki ẹ jẹ ki onirin rin irin ẹsẹ rẹ, laiye Ọba!!!

Ẹ KU AFOJU S'ỌNA.

A gbọ pe awọn Ọgbẹni Macaulay, Akingbade ati Craig, ti nwọn lọ si'lu Ọba lẹnu oșu meje to kọja yio de sibi ni

*Thursday* ọsẹ to mbọ. Njẹ ẹnyin ẹbi, ẹ ku a f'oju s'ọna.

AWỌN ỌMỌ ALUFA IPORO NAWO BI ẸLẸDA.

A gbọ wipe awọn ọmọ Alufa Iporo, Ẹni-ọwọ E. W. George Olõgbe lo ranṣẹ *Tablet* ti a sọro rẹ lọsẹ to kọja ati pe ki iṣẹ Ọgbẹni Williams Bọlaji George nikan ni o ni ọwọ ninu ohun iranti na.

ỌNA M'OLE, AWO YA ! ! !

Ni ọjọ *Tuesday* ( Atalata ) ọsẹ yi, awọn ọmọbinrin ọmọde-mọṣọ meji kan ti nwọn ti wọ aṣọ gaga, gbe sunmọmi ole lọ jale ni Ṣabu *Lagos Stores* ni Ẹhin-ọgba; bi nwọn ti de ibẹ pẹlu apoti pali kan ati Tim-tim ( *Cushion* ) alayinrin, bẹni ọkan ninu wọn si sọ fun Akọwe Ṣabu na pe ki o mu aṣọ ti o wa loke fun on ni ori ikọ ; bi Akọwe yi ti ṣe bẹ, bẹni awọn "ara ile wa" nbu irẹ jẹ ti nwọn nbu irẹ s'apo nipa kiko aṣọ ṣẹda igan mẹrinla ti a npe ni *Silk Madras* sinu apoti pali ti nwọn mu dani : nigbati o ṣe, nwọn ni ki Akọwe na sọkalẹ ki o tun mu aṣọ miran fun wọn ni Ṣabu na, o si ṣe bẹ ; ṣugbọn gẹgẹ bi nwọn ti nṣe si, ara fu u o si dakẹ ; nikẹhin awọn ọmọ'binrin yi ni nwọn ṣi nlọ sibomiran na, bẹni Akọwe na bi nwọn pe ki on wo ohun ti nwọn ko sinu apoti pali, o di womi-nwo-ẹ ; nigbati a si ṣi apoti pali yi, a ri aṣọ ṣẹda wọnyi nibẹ, ti o jẹ oni pọwun mẹrindilọgbọn ( £26 ) bẹni Akọwe yi si gba awọn Igan aṣọ na lọwọ wọn, o si ti wọn si ita ; awọn ọmọde si pariwo ole le wọn lori gẽ. Nigbati itiju na pọ, ẹnikan to wa nibẹ fi wọn pamọ sinu Ile kan titi awọn ọmọde fi tuka ; lẹhinna ni awọn Obinrin Afinju Ole yi, fi ẹhin-ẹhin rin lọ sile. Ti awọn ti a wi yi ba nka Iwe '*Eko Akete*' yi, yio ma ṣe kì ninu wọn ! ! !

Ẹ KU EWU ỌDUN.

Ki "*Eko Akete*" to tun bọ sode lẹhin t' oni, Ọdun Keresimesi yio ti de yio si ti lọ nitorina a ki ẹnyin ọrẹ wa gbogbo, ni 'le, l'oko, l'ajo, ni akisilẹ. Ẹ ku ewu Ọdun !

ẸNYIN-A-GBA "*EKO AKETE*" Ẹ PE WA L' ENIA

Inu wa yio dun bi gbogbo awọn ọ[illegible] wa A-gba "*Eko Akete*" ba tete tun [illegible] owo gbigba Iwe-irohin na ranṣẹ si wa nitori pupọ ni owo a-san-silẹ wọn ta[illegible] loṣu yi.

ABỌ O !

A ki Ọgbẹni A. Bankọle Williams akọwe agba ni Ile Iṣẹ-waya *Railway* ni Minna kabọ ; ọgbẹni na gba isinmi wa le lati ẹnu iṣẹ rẹ ni lọlọyi.

Alafia k' ẹ ba 'le?

IKORE TO KA-NKA.

*Pastor* A. Adedeji Iṣọla yio sọ kutupu ọrọ ninu wasi rẹ ti yio ṣe ni Isin Ikore awọn *Church Brotherhood* ni ọgbọn ọjọ oṣu yi ni Ilupesi ni agogo mẹfa abọ alẹ.

BALẸ ỌKỌ ILU FỌ'FE.

Ọpọlọpọ ọrọ ni Balẹ Ilu Ọgbẹni Henry Carr I.S.O. sọ ni ṣiṣi Ṣukuru ti awọn Ijọ Ọmọ Ibilẹ ni Ita Tinubu, ni *Thursday* ọsẹ yi. A o sọ nipa rẹ l'ọsẹ to mbọ.

---

**AYILUKA'S BRAGGADOCIO.**

In further reply to Ayiluka's vapourings in the last issue of *The African Messenger*, we would advise him to ponder over, these deep, yet heart-searching words from the Book of books :—

"Let him that *thinketh he standeth*, take heed lest he fall."

(ITALICS OURS.)

Ed. E.A.

---

## *Open Letters.*

No. 42.

**TO OUR READERS.**

Friends,

Before the next issue of our paper sees the light of day Christmas would have come and gone : we therefore seize this opportunity to wish you and yours at home and abroad, A Merry, Pleasant, Xmas in anticipation.

Health to your body.
Peace to your soul,
Health to your purse
We wish you no worse !!!

EKO AKETE.

## KILO KAN IMALE PẸLU KERESIMESI.

Ko si ẹniti yio ka iwe ti Apostili A. O. Ijaoye kọ sinu *Eleti Ọfẹ* ti ọsẹ yi ti ko ni dupẹ fun u nipa imọran oniyebiye ti o gba awọn to nmura lati ṣe aisun ọdun Keresimesi to de tan yi. Gbolohun kan ni o yẹ ki a dahun ninu awọn ọrọ na—nibi ti o gbe sọ pe on gbọ pe awọn ọmọ Imale l'onba aisun ọdun na jẹ. Ṣugbọn ọrọ na ti oju suni. Kilo kan ọmọ Imale pẹlu Keresimesi ? Kilati pin itan aja ki o to kan Lemọmu ? Lotọ ọpọlọpọ awọn ọmọ Imale ni iwa jagidi-jagan lọwọ ṣugbọn bi ti ọdun Keresimesi kọ. Ki li a nfi ọrọ bọpo bọyọ si ? Ti a ba fẹ ba awọn ọmọ Kiriyo wi nipa ọti amu-ṣubu sita lalẹ ọjọ yi ki a ba wọn wi. Imale kan ti ori rẹ pe ti o jẹ ma ṣiwere kiri lalẹ aisun Keresimesi ko si. Pẹlupẹlu awọn Imale ko mọ idi ki a ma muti ki a si ma ṣubu kiri adugbo ki a ma ni basi ẹran kan ninu ikoko. Njẹ awọn ọmọ Imale lo hu iwakiwa ti wọn hu ni Ipade *Keswick* eṣin ti o bi awọn agba Kiriyo ninu ? Ẹ ko ba ole wi ẹ ni onihun ko fihun rẹ sibi to dara.

Nipa ti pe Imale nṣe ọdun Kiriyo, a ko le fẹ iyẹn ku, bẹ si ni a ko le fẹ Kiriyo to lọwọ ninu Ẹran-Ileya ku.

ADEKANBI.

---

## ***Wesleyan Trinity Church, Tinubu.***

There will be a Carol Service at the above Church on Xmas Eve, December 24, 1923, at 7.30 o'clock in the evening, when charming and melodious Christmas Carols will be sung by the Choir. The programme for this year contains many new and original carols and is fuller than any that has been issued for Christmas season on previous occasions.

A very successful evening, as usual, is therefore anticipated for both the singers and the listeners. Members and visiting friends are requested to procure in time their copies of the words of Carols which may be obtained from Messrs. S. Thomas & Co., Tinubu Square, and also at the gate before the Service, on Xmas Eve, at six-pence per copy. Collection and donations will be taken at the Service in aid of the Choir Fund. Good Luck to E. J. and his Choir.

## ISIN IKORE ATI ISỌJI NI IJẸBU-ODE.

### II.

"Yiniyini kẹni ṣe ni." Ni agogo mẹsan orọ *Thursday* Olulana pẹlu ero diẹ lọ bẹ Awujalẹ ti Ijẹbu Ode wo ati lati dupẹ atijọ fun u: nigbati a de ibẹ "Alaye" na yẹ wa si lọpọlọpọ, o ṣe wa lalejo to tọ, to si yẹ (Awujalẹ na ni ẹniti o fun wa ni ilẹ ti *Church* wa wa loni ati titi lai, k Ọlọrun tubọ sun ẹmi rẹ siwaju si i—Amin ati Amin) Olulana si dupẹ fun u pupọ fun iyẹsi to yẹsi l'ọdun kẹta lọhun nigbati Olulana lọ sibẹ, Olulana si gba niyanju ọpọlọpọ, lẹhin iyẹsi ati igẹ gbogbo, a fi ibẹ silẹ; lẹhinna a wa bẹ ile ẹkọ wo pẹlu Olulana, bi ati dasẹ l'ẹnu ọna Ile-ẹkọ na gbogbo awọn ọmọ ile ẹkọ dide wiri (bi igbati jagunjagun iba dide) nwọn si ki Olulana ati awa akoyẹyẹ rẹ *good morning sirs, good morning sirs*: Olulana si bẹ wọn wo *class by class*. Orukọ awọn olukọ ile ẹkọ na niwọnyi :—

Messrs S. A. Ọnasanya, (Aṣoju olukọ agba, ati atẹduru) G. I. Ọkẹgẹ, A. O. Ẹbọda, A. S. Ṣokalẹ, S. Alli, L. Merafa, Misses. A. Owuyẹ (*head mistress*) Vic. A. Ọnabanjọ ati B. O. Ẹrufa. Olulana si gba ati olukọ ati akẹkọ niyanju to larinrin, ti mo si ro pe bi nwọn ba tilẹ gbagbe ohunkohun, nwọn ki yio gbagbe itan nipa Ere Anfani.

Awọn ọmọ si fi ayọ wọn han nipa ṣiṣere idaraya (*Athletic Sports*) diẹ fun Olulana. Ere na si wu ni lori lọpọlọpọ. Ninu ere afigi-fo (*high jump*) awọn ọmọ yẹn nfo "kulagbe" ninu fifo, nwọn ṣe gbogbo awọn ere laṣe gbadun. Olulana ṣọwọ ẹhin fun ọga afigi fo (*the highest jumper*) ati awọn aja-ajaṣe-fakun (*winners of the tug of war.*) Eyi fi han pe awọn olukọ ko jafara rara ninu iṣẹ wọn larin awọn akẹkọ wọn.

Ati pẹlu gbogbo awọn olukọ-kunrin ni mo rope nwọn jẹ ero Ijọ wa, ẹni na ni omidan Vicioria A. Ọnabanjọ, agunlẹhinju, omidan na si jẹ ọmọbinrin Ọgbẹni I. O. Ọnabanjọ baba isalẹ ati baba Ijọ Brotherhood ti Ijẹbu-ode.

Niwọn agogo mọkanla nlọ lu, ipade wa pẹlu awọn obinrin, Olulana li o ṣe alakoso ipade na, o si ba wọn sọrọ iṣiri pupọ bi o ti jẹ pe lọdọ awọn obirin ni ilọsiwaju ati iṣubu Ijọ wa, o si fi han wọn bi o ti jẹ pe bi ọkunrin ti ni ẹgbẹ bẹ gẹgẹ l'obinrin si ni lati ni ẹgbẹ fun ilọsiwaju Ijọ. Gbogbo awọn obinrin si gba lati da ẹgbẹ silẹ...... ipade na si tuka, lẹhin ti a pari eto gbogbo.

Aragbabu ni isin alẹ na, enia bu aiya, Họwu! enia pọju, "wa- ibi-gba" ni iwasu alẹ na fun tana.

[ *Koi ti pari* ]

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, DECEMBER 22, 1923.

## KERESIMESI, ỌDUN DE!!!

Wàràwèré Ọdun Keresimesi tun dun ba ni lẹkan si lori ilẹ alâyè; fun eyi, ã bá ni ẹgbẹrun ahọn bi ti ina, kò tó dupẹ lọwọ Olodumare nitori aimọye ore rẹ lori wa ni lila ọṣu mejila miran kọja eyiti ao sinku rẹ lọsẹ to mbọ; a fẹrẹ le sọ pe ninu gbogbo ọdun ọjọ Ibi Olukọ ni nla yi, ani Jesu Kristi—Anabi Isa ọmọ Mọriamọ—ki a sọ lede ti awọn Musulumi ọrẹ wa, ti a ti nṣe bọ̀ lati nkan bi ọdun kẹwa wa, kosi ọdun to "gbẹ" to si fi pupọ enia ni ilẹ yi làkàlàkà to ọdun yi. Ewo ni kò tó rò nibẹ? ti oku ti gbogbo òwò dà ni, tabi ti ọ̀dá owo ni ilu, ti airiṣẹṣe ọpọlọpọ awọn enia ni, tabi ti atẹhinku loriṣiriṣi ọna? bi ọdun 1923 yi tilẹ jẹ ọdun ti o nfo ni (*Leap Year*) ọran ko gbọdọ to yi; nigbati a tun wo ilu lọ gara, a ri pe ṣaṣa ile ni a kun l'ẹfun, gẹgẹbi kikun-ile-ọdun; ki lo mu aikun ọpọlọpọ ile miran wa? ko si ohun meji ju ohun ti a ti sọ loke iwe yi lọ; eyini ni ti gbogbo òwò ti ko gberi.

Ẹniti o ni ọja ẹlẹgbẹrun pọun (*£1,000*) fun tita, ti ko si jere ẹgbẹrun kọbọ lori rẹ, kaka bẹ ti o tun padanu ja-nrẹrẹ, kọ ni ara ma ya pe on ṣe ohun kan gunmọ?

Tabi ẹniti a da duro nibi iṣẹ ni 'le oyinbo lojiji nitori aidara òwò ti oluwarẹ ni obinrin ati awọn majeṣi ni 'le ti o ngbọ bukata wọn kọ ni ori ma ya pe on kun ile? tabi ẹniti ibajẹ òwò tabi awọn Alagbeda da ni gbese kọ lo ma roju ile kikun ati nkan bawọnni? tabi ẹniti o ni ọja ni Ṣabu, ti ọja na si nmọ̀ loju, lalai ta rara, ti oyinbo oniṣowo rẹ si nfã a bi máfã lati wa *balance*, kọ ni iba mã ni on nri aye ile kikun? Ni gasikiya, Bi Ile ko dun, bi Igbẹ ni 'lu nri: a ṣá ri ẹniti a daduro nibiṣẹ *Railway* lapapa ndo-do, laiṣẹ lairo, laifi ẹsẹ tẹ ôkan wọn mọlẹ nibẹ, lẹhin igbati o ti ṣiṣẹ nibẹ fun ọdun mọ-kan-le-lo-gun gbako; kini ẹ rope ero irufẹ ẹnibẹ le jẹ lakoko yi?

Nitotọ a mọ pe ẹniti ọdun ba dun ba, o yẹ ki o yọ, a ko si ni ki ẹnikẹni má yọ; ṣugbọn ki a kiyesara ki a ma yọ ayọ ti Akere yọ to fi itan ṣọ.

A ri ti ọdun yi ná, o ku ti ọmọ inu rẹ. Ki Baba maṣai ṣe ọdun Keresimesi yi ni abo ọdun fun olukuluku wa tobẹ ti a o fi le mã kọrin pe:—

Awa 'o mã yọ̀
Awa 'o ma yọ̀
Ọjọ-Ibi Jesu Ọga de o,
Awa 'o ma yọ̀
Ara yẹn, Ara yẹn, Ara yẹn
Awa 'o mã yọ̀!!!

## GOOD MARKET.

At H. Campos's Shops, 7, Campbell Street, 2, Faji Market, and 63, Ọdunlami Street, Lagos.

## NERVE TONIC.

Moloke Mone A. & B. 6/- & 5/- a bottle.
Bula Matadi 7/- a bottle.

**WONDERFUL GONORRHOEA SPECIFIC WITH INSTANT RELIEF, WILL CURE THE MOST OBSTINATE CASES.**

Euregon Pillen Pills at 3/6d. a Packet.
Euregon Liquid 4/- a bottle.
Gramophone records 10 ins. & 12 ins. Best Cigars superior quality. Provisions in endless variety.

CASH ONLY.

## Change of Address.

Mr. Karimu Kotun on behalf of his Firm begs to inform the Public that he is removing their Show-room from No. 20, Porto-Novo Market Street & Broad Street, Lagos, to No. 3, King Docemo Street, Lagos, (Babu Kaman Ala) with effect from the last day of January, 1924, and that all communications intended for him or his Firm from that date should be directed to the latter address.

# LOOK OUT

**For the OPENING of**

# Lever Stores

## LIMITED,

## BROAD STREET, LAGOS.

A

**WONDERFUL ASSORTMENT OF GOODS**

AND

**Nothing in the Store over 1s.**

***"VARIETY AND VALUE."***

---

## ỌRẸ

Ẹ mura de ṣiṣi ṢABU TITUN ti awọn Oyinbo **LEVER,** Onișowo-Bombata, yio ṣi ni lọlọyi ni opopo nla (*Broad Street,* Ile Bucknor.) Orișiriși Ọja ni mbẹ nibẹ ni ọpọku-ọyọku.

Kami-kami-kami ni gbogbo wọn nję, kosi-ohun-ta-fi nkan a, ẹnikeji.

## Ẹ WA WO.

# ORUKỌ WO L'O DÙN TO YI, EMANUEL.

[ *Lati ọwọ* ATARI AJANAKU. ]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo juba o,

Ọjọ mẹrin loni, (25th December,) ni ojọ ti awọn Onigbagbọ ya si oto ni gbogbo aiye bi Ọjọ-ibi Jesu Kristi, ẹniti awọn Imale npe ni *Anabi Isa*. Ọjọ na jẹ ọjọ pataki fun awọn Onigbagbọ, o si jẹ ọjọ ti t'ọkunrin, t'obirin, t'ọmọde, t'agba njo, nyọ, ti nwọn a si ma fo soke sibi-sọhun, pẹlu orin "KERESIMESI," ọdun de.

Li aisi ani-ani, Jesu Kristi jẹ Oji'ṣẹ Ọlọrun pataki li aiye, a ko si le sọ ọrọ rẹ li aidarukọ awọn ẹni nla ati abami enia miran ti o ti wa si aiye ṣiwaju rẹ; awọn ẹni bi:—Gotama Buddha, Confucius ati awọn ẹlomiran ti o da Ẹsin Judaism, Hinduism, Paaseism, Taoism ati oriṣiriṣi Ẹsin miran silẹ ṣiwaju Ẹsin Igbagbọ ti a npe ni *Christianity*, ki o to wa kan Ẹsin Imale ti a npe ni *Mohammedanism*, li ẹhin ẹgbẹta ọdun ti Jesu Kristi ti goke re ọrun.

Bi o tilẹ jẹ wipe ko si alamọla ti o ma wipe ti on ko'yi, bẹni ko si ẹnikẹni ninu awọn ẹni nla ti a darukọ wọnyi, ti Ẹsin rẹ ko dara li oju rẹ ju ti ẹnikeji lo, ani li oju awọn Onigbagbọ Aguda (*Roman Catholic,*) irọ ni Onigbagbọ Gẹsi (*Anglican Communion,*) Imale ati Ẹlẹsin miran—irọ ni gbogbo wọn npa. Eyi li o jẹ ki a wi bi Babalawo wipe "Ọrunmila"! ọrun nikanṣoṣo li o mọ ẹniti yio la a; ki olukuluku enia sa toju iwa rẹ, ki o ma si ṣe ohunkohun ti o lodi si ifẹ Ọlọrun Olodumare.

Gẹgẹ bi iṣiro awọn ti a npe ni *Geologists* tabi awọn ti a le ka si Ọmọran, ti o nmọ oyun inu igbin, o di ẹgbāsan ọkẹ odun (360,000,000 years) li oni, ti Alaiye ti da aiye, li arin eyiti oniruru igba mejila (*12 Geological periods*) ti rekoja; igba ẹranko, igba ewebẹ ati eweko-igbẹ, igba okuta ati irin, ati igba nkan miran, ki o to wa kan akoko ikẹhin ti awa ẹda de inu aiye.

Gẹgẹ bi a ti ka a, awọn enia ti o kọkọ de aiye, iṣẹ ọdẹ ni nwọn nṣe, nwọn a si ma gbe inu iho bi ẹranko igbẹ. Ọfa ati ọrun ti nwọn fi nṣe ọdẹ ni igbana ko gbamuṣe bi ti isisiyi, ẹniti o ba si fẹ lati mọ bi nwọn ti ri gan, o le wọ Ọkọ lọ si ilu Oyinbo, yio si ri wọn ni *British Museum* nibẹ. Pẹlu iṣẹ ọdẹ, awọn ẹni lailai wọnyi nda oko ti nwọn ngbin ohun jijẹ bi iṣu, agbado ati nkan miran si, nwọn a si ma fi ọgbọn ati ẹtan sọ ọpọlọpọ ẹranko igbẹ di ẹran ile; nipa ṣiṣe bẹ, ni ewurẹ, aja, ologbo, malu, ẹlẹdẹ, ẹiyẹle, adiẹ, ẹtu, tolotolo, pẹpẹiyẹ, aiyekotọ ati nkan ọsin miran ṣe di ara ile.

Ohun alumọni bi ilẹkẹ, sẹgi wa nigbana, ṣugbọn ko si wura tabi fadaka titi di iwọn ẹgbẹrin odun ti o koja, nigbati awọn ilu ti a npe ni Peru, (ki nṣe Ipẹru ti Ijẹbu ọmọ alarẹ o) bẹrẹ si wa wura.

Gbogbo Iwe-itan iṣẹda-aiye ti o wa ni isisiyi jẹ ọmọ kekere jojolo li ẹgbẹ ọdun gboro ti Alaiye ti da aiye, awọn ti a si npe ni *Ethnologist* sọ fun wa wipe oniruru orilẹ-ede marun li o wa, awọn mararun yi si jẹ ọmọ ẹnikanṣoṣo, ẹniti Bibeli ati Alkoran pe fun wa ni Adam, ti awọn baba nla wa pe ni Odudua; ti Oyinbo Darwin si pe ni ọbọ tabi Lagido.

Ọkan ninu orilẹ-ede pataki marun yi ni orilẹ-ede enia dudu, ọkan ninu eyiti Egypt nṣe—Egypt, iṣẹdalẹ ile ọgbọn, nibiti ilaju kọkọ bẹrẹ, ki o to de ilu Greece, ati ilu Rome, ki o to ṣẹṣẹ wa de ilu awọn Oyinbo ti o dabi ẹniti o jẹ oye "Ọmọ-gbọn-ju-baba-lọ" nisisiyi.

Fun ọpọlọpọ ọdun ti enia dudu ti nṣe ara ile, Oyinbo nṣe ara oko; nigbati enia dudu ti nwọ bata, ti nwọn ndi kọla (*Collar,*) bantẹ ni awọn Oyinbo nsan; nigbati Ọgbẹni Euclid a-du-ma-dapọ nṣe *Geometry*, iwe iṣiro nla, awọn Oyinbo ko le ṣe iṣiro owo ti awọn "elebisi" (*A. B. C.*) npe ni adiṣọn (*addition.*) Li aifa a gun lọ titi, ni iwọn ẹgbẹdogun ọdun ki a to bi Jesu, ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti Anabi Mọhọmọdu tabi awọn Woli miran, enia dudu ti mọ Ọlọrun, nwọn si ti nsin I, nigbati awọn Oyinbo nbọ õrùn, oṣupa, irawọ, ãrá, igi ati oriṣa miran ti ko nilari.

Ni ilu Gẹsi loni, oye ojiṣẹ Ọlọrun ti o ga julọ nibẹ ni oye *Archbishop* ti *Canterbury*, enia dudu ti a npe ni Saint Augustine, ẹniti o mu Ẹsin Igbagbọ lọ si ilu Gẹsi ni iwọn egbeje ọdun sẹhin (A.D. 597) ni o kọkọ jẹ oye nla *Archbishop* ti *Canterbury* ti a nsọ ọrọ rẹ yi. Eyi fihan ni gbangba wipe li ọjọ atetekọṣe, Ọlọrun ko ṣe enia dudu ni ẹni yẹpẹrẹ, ṣugbọn l'oni nkọ? Ẹ ko ri wa bayi, ọbọgilawọ; boya aiye ijẹkujẹ, arankan, anikanjọpọn ati iwa buruku wa miran li o jẹ ki atẹ ilẹkẹ enia dudu di atẹ ọrunla loni. Ki Ọlọrun jọwọ pa sã da si rere fun wa, ki O si dari gbogbo ẹṣẹ wa ji wa.

*Africa shall rise, Africa shall rise*: Enia dudu yio dide, enia dudu yio dide, ni a ngbọ li ojojumọ—ọpọlọpọ enia si ro wipe ninu iwa agbenigbunọba, agabagebe, alọnilọwọgba, tẹmbẹlẹkun, ole, eke, agbere, abinu-ẹni; jijẹ talaka, opó ati alainibaba ni iyà ni idide enia dudu wa. O ṣe! Bẹkọ rara.

O nlọ si ẹgbã ọdun l'oni ti Jesu Kristi wa si aiye, ko si si opitan-ko-pitan kan ti o le fi ọwọ sọ'ya wipe ọjọ kẹdọgbọn oṣu December (December 25, A.D. 1,) ni a bi Jesu si Bethlehem ni ilẹ Judea, a si ri i daju gbangba wipe December 25th ki nṣe Ọjọ-ibi Kristi. Titi Jesu fi tẹrigba'ṣọ, a ko ri i ka lati Iwe Matteu titi de Iwe Ifihan wipe Jesu papa ṣe iranti Ọjọ-ibi rẹ lẹkan ri, o si lẹ ni

ẹdẹgbẹta ọdun lẹhin iku rẹ, ki awọn Onigbagbọ ti o wa ni ilu Greece ati Rome ti o fi ẹnu ṣ'ọkan lati yan ọjọ kẹdọgbọn oṣu December si ọtọ bi Ọjọ-ibi Jesu, ati lati ma ṣe ariya ayọ nla li ọjọ na; ki nṣe nitori nkan meji ni nwọn ṣe yan ọjọ kan ni oṣu December, bikoṣe lati pa ina ariya isin oriṣa nla ti awọn abọriṣa nṣe li ọdọdun oṣu December li akoko na, ni ilu Greece ati Rome. Ere ajọdun yi ti awọn Onigbagbọ bẹrẹ si ṣe, ti nwọn si njo kakiri ilu, ti nwọn si nkọrin "KERESIMESI," ọdun de, sọ ọpọlọpọ abọriṣa igbana di Onigbagbọ.

Bi a ko tilẹ le sọ yala bi ijọ kini oṣu *January*, tabi ijọ keji oṣu *February*, tabi ijọ kẹta oṣu *March* ni a bi Jesu ni o, ọkan da wa loju gbangba pe Maria iya rẹ da ẹjẹ si l'oju n'ijọ kan ṣa dandan, "Joseph gbẹnagbẹna (*Carpenter*) ni a si ṣebi iṣe baba Jesu, nitori on ni o gbe iya rẹ ni iyawo."

Ofin mẹwa pere ni Jesu ba lode aiye pẹlu ti awọn Farisi, ṣugbọn l'oni nkọ? Ofin *Criminal Code* le ni ẹgbẹjọ. Arufin to wa lakoko Jesu ati oniwakiwa to wa l'akoko rẹ pẹlu dabi ẹnipe ko to nkan kan l'ẹgbẹ Arufin ati Aniwakiwa enia to wa nisisiyi, bẹni igbagbọ ni awọn onigbagbọ wipe "Jesu iwọ ti o ko ẹṣẹ aiye lọ, ṣanu fun wa." Loju temi, o dabi ẹni wipe awọn onigbagbọ rope awọn le da oriṣiriṣi ẹṣẹ lati *Monday* titi di Satide, to ba si di ijọ osẹ (*Sunday*) ti nwọn ba ti lọ si Ṣọṣi, ti wọn ba si le jaja wipe "Jesu iwọ ti o ko ẹṣẹ aiye lọ, ṣanu fun wa," nwọn ti ri idariji gba, nwọn tun le bẹrẹ si da ẹṣẹ titun lati *Monday* miran di Satide. Onigbagbọ bẹ ntan ara wọn jẹ ni i, o si da ni loju pe lẹhin ọdun diẹ, lẹhin igba diẹ, nwọn a mọ pe kijipa ko nṣe awọ.

Onigbagbọ totọ melo lo wa l'Eko, onigbagbọ awo lo fẹ ọmọ-ni-keji rẹ bi ara rẹ, bi o ba ko pa a, bi o ko ba ko bu u lẹsẹ ko lo pọ larin onigbagbọ isisiyi. Agbalagba ko fẹran ọmọde, ọmọde ko bẹru agba, ọkọ ko mọ ipo rẹ, aya nforu bọju, on ṣe ẹṣu mo bi, ẹgba mo bi kakiri ile onile nitori ati r'owo ra aran Efiniwa. Ṣiọ! ijọ melo lẹ ma ṣe eyi gba. Epo to wa lori Ṣigidi onigbagbọ miran kun ṣago, laika igbadi, ikobẹrẹ, akaraba ati aruntu. Ewọ! A ha fi Kristi kọ nyin bẹ, ẹnyin Onigbagbọ Eko?

Ọdun yi ọdun 1923 nrekọja lọ, ọdun miran si nsare tete lati gba ipo rẹ, ọdun yi abami ọdun ni papa la'rin wa l'Eko. Ọdun ti Ọgbẹni Makọli ati awọn jakan-jakan miran da ẹgbẹ *Democratic Party* silẹ, iru eyiti ko si ri ni gbogbo ilu *Nigeria*, ọdun ti a yan enia mẹta Ọgbẹni Shyngle, Moore ati Jonse si Igbimọ aṣelu (*Legislative Council*) ọdun ti a fun ọlọla Donald Cameron ọrẹ wa ni oye K.B.E, ọdun ti ọlọla Donald Kingdon Attorney-General ṣe iwe ofin nla nla mẹrin, ọdun ti a fun Dokita Oguntọla Ṣapara ni oye I.S.O, ọdun ti Ọgbẹni Henry Carr, balẹ ilu ṣi ile ẹkọ ọmọ ibilẹ (*U.N.A. School*) ọdun ti ologbe Lemọmu Buraimọ ku, ọdun ti a fi Afa Ligali olohun iyọ jẹ Lemọmu, ti Tijani ẹgbọn rẹ si nba du ipo na, ọdun ti Ọgbẹni J. O. Beckley, J. W. Vaughan, aya Ọgbẹni T. K. E. Phillips, arẹwa ọmọ Biṣọpu Oluwọle, Alhaji Alli Fahm oninurere, Ipayẹ Bologun, J. N. John ati awọn enia pataki miran di ologbe, ọdun ti Lọya kan w'ẹwọn, ti ọkan pokunso, ti ọkan si ku iku gbigbona ni gbangba Kotu, ọdun ti Ọgbẹni Joseph Aribisala ku lojiji ni Kotu, ti adiẹ kan bi ọmọ ẹlẹsẹ mẹrin ni Lafiaji, ti Dokita Savage da Iwe-irohin *Nigerian Spectator*, ti Ọgbẹni Akitan da *Eleti-Ọfẹ* ati Ọgbẹni Braithwaite da *Nigerian Advocate* silẹ ninu eyiti "Cicero" nfi gege dara bi *Scrutator*, awọn ọdọmọkọnrin ọkọwe mejeji ti a mọ ti a ko gbọdọ daruko, ọdun ti Rọla ati Ronkẹ ọmọ Bishop Oluwọle ati Labisi ọmọ Ogunbiyi de lati ilu oyinbo, ọdun ti ọpọlọpọ enia ni'lu d'onigbese, ti ẹni to ti ntẹ'ba, to nse'bẹ, to ngun,yan di ẹni to tun nfi ewe da'wujẹ. Iba ọjọ diẹ to ku k'ọdun yi pari, Ọlọrun nikan lo mọ ẹniti yio ba a; ṣugbọn adura mi ni pe ki Keresimesi yi le jẹ ọdun rere fun gbogbo wa, ko si ba wa pẹlu alafia ati ara lile.

A ko nri'di okun,
A ko nri'di ọsa,
A ko nri'di ọmọ onigelegele;
Iku to ba ni on fẹ ri nyin l'ọdun yi, bombata yio bo mọlẹ fun nyin, bombata,
Arun tabi ohunkohun buruku to ba ni on fẹ ri nyin l'ọdun yi, bombata yio bo mọlẹ fun nyin, bombata.
Ire, ire, ire lẹ o ma ri porogodo. Aṣẹ.

*A Merry Xmas to you all.*

Emi ni tirẹ nitotọ,
ATARI AJANAKU

---

FUN IRANLỌWỌ "EKO AKETE."

| | | £ | s. | d. |
|---|---|---|---|---|
| Owo ti a ti ri gba | ... | 5 | 14 | 0 |
| Ọgbẹni A. Kayode | ... | 0 | 10 | 6 |
| ,, Duro Thomas | ... | 0 | 10 | 0 |
| ,, A. Alhaji Davies | ... | 0 | 5 | 0 |
| ,, Ayọdele Williams | ... | 0 | 5 | 0 |
| ,, E. O. Oni | ... | 0 | 5 | 0 |
| ,, M. M. Ṣonibarẹ | ... | 0 | 5 | 0 |
| ,, James A. Sule | ... | 0 | 5 | 0 |
| ,, Jaiyeọla Agbe | ... | 0 | 5 | 0 |
| ,, Sam Clay | ... | 0 | 2 | 0 |
| | | £7 | 19 | 6 |

## Preachers for To-morrow.

### AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo ikoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rt. Rev. Bp. I. Oluwole |
| 6.30 p.m. | | (In charge) |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do. |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do. | ,, E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Ereko | ,, Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do. | ,, E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | ,, S. A. Pearce |
| 7 p.m. | do. | ,, A. N. Cole |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Bro. E. E. Ajọṣe |
| 7 p.m. | do | Rev. S. A. Pearce |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | do. | Bro. Josiah Laleye |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. J. H. Lawson |
| 7 p.m. | do. | Rev. M. B. Newton |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. J. W. Bara |
| 6.30 p.m. | | Bro. E. O. Peters |
| 9 a.m. | Zion | Rev. J. A. Wright |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. N. J. D. Shomuji |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. S. A. Fatolu |
| 4.30 p.m. | do. | ,, T. J. A. Green |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. R. O. Macaulay |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Bro. Jariogbe Tubi |
| 6 p.m. | | Bro. John Apena |

**EBENEZER (BAPTIST)**

9 a.m.
6.30 p.m. Bro. J. F. Oshodi

**BROTHERHOOD**

7.30 a.m. Ilupesi Bro. Akinwande Adegun
7 p.m. Prof. Adeoye Deniga

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service I. A. Shitta
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajose
(Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon, Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

10 a.m. Capt. A. A. da Costa
7 p.m. Lieut Colonel George H. Souter

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. T. Terrell

---

### IGBẸ L' OWO WÀ.

**LAGOS—EKURO.**

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Oja (*Produce*) l' ọṣẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African Association, John Holt, Miller Bros. Cooperative Wholesale Society Ltd., Jurgens Colonial Product.

£14 5s.—£15 fun *ton* kan

EPO.

£24 10s.—£26 10 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£14—£17 10 fun *ton* kan bakanna.

**KANO—COMPETITIVE PRICES**

Ground Nuts—£14 10s.—£15 per ton
Skins 1/9 per lb, Hides 5d per lb

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION.*

TO

**S. I. M. Johnson,**
9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

---

# Chairs! Chairs!! Chairs!!!

For hire at Ilupesi Hall, Enu-owa, Lagos.

REDUCED PRICE, 1½D. PER CHAIR, PER DAY.

Apply to the MANAGER,
J. A. OSHODI,
26, Ọbun-Eko Street,
LAGOS.

---

# AGA, AGA, AGA.

FUN YIYA NI ILUPESI, ẸNU-ỌWA, LI EKO.

OWO PỌKU NI A FI NYA NI NISISIYI. (1½D.) KỌBỌ KAN PẸLU ABỌ.

Lọ si ọdọ ALABOJUTO,!
Ọgbẹni J. A. OSHODI,
No. 26, ITA ỌBUN-EKO,
LI EKO.

---

## The Union Night School.

FOUNDED JAN. 1923.

The School prepares candidates for **Cambridge**, Preceptors and Government Clerical **Examinations** and also teaches all Infant and Primary subjects, Yoruba inclusive.

The School opens on Mondays, Wednesdays, and Fridays in the Breadfruit School (Top floor)

For further particulars apply to

*THE SECRETARY,*
Union Night School,
P.O. Box 121,
Lagos.

---

## ILE IWE ALẸ.

A da Ile-iwe alẹ silẹ fun gbogbo ọmọ Ile-iwe ati oşişẹ pẹlupẹlu fun awọn ti o nfẹ lati şe idanwo fun işẹ Ọba ati *Cambridge*, a si nkọ iwe Yoruba nibẹ. A nşe Ile-iwe yi ni ọjọ *Monday*, *Wednesday* ati *Friday* ni agogo meje abọ alẹ ni Ile-iwe *Breadfruit* (Loke.)

---

# GOOD BARGAIN

IN

**Bunting Flags, Folding Chairs and Benches.**

CANNOT BE BEATEN.

Folding Chairs, Buntings Flags and Benches suitable for Picnics, Wedding Festivities, Entertainment, Social Gathering, etc., may be had on hire at the following very reasonable rates:—

FOLDING CHAIRS, 1½d. each per day.

FLAGS, etc., "Large" 6d. each, per day.

" " "Small" 3d. each, per day.

**Personal inspection invited. You are sure to be satisfied.**

Arrangements for delivery, etc., can also be made at very little extra cost.

Apply to:—SALAWU BANJOH.
*Manager,*
"Enia-Şoro" Cottage,
24, Porter Street, (Idunşagbe,)
LAGOS.

## A. KESSLER,

7, Labinjo Lane. P.O. Box 459.

SAMPLE SHOW ROOM.

*Agent for* ARNOLD SCHLESINGER,
The German Trading House,
Hamburg, Germany.

SAMPLES OF ALL GOODS FOR THE AFRICAN MARKET EXHIBITED.

The Mundlos Hand and Foot Sewing Machine, as well as the Alder Foot Sewing Machines,

*Are always obtainable from stock or for order and are ornaments for every body's house.*

**FOR SALE**

The Typewriter "Perkeo" £9. 5. 0.

Cycles

Toys, that is what you want for Xmas.

24 hours Kitchen Clocks—a good clock for a good time.

Earthenware.

Descent Wristlet Watches sh. 8/- and sh. 4/3 each.

Carpets to make your house comfortable.

Clay Pipes, Razors, Fez Caps, Hanging Lamps, etc.

As the fire wants the wood to burn, you want my Beer to quench your thirst, therefore buy the

LION BEER (Pilsener Light) 30/- per case.

TUCHER BEER do. 34/- per case.

And for happy hours take a case of my requisite CHAMPAGNE per case £3. 5. 0.

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos. ...

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

## Aworan Alarabara.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi şe ile li ọşọ. A ni ti titẹ oku Jesu, ti igbati a da a li ẹbi iku, ti Onjẹ-alẹ ikẹhin. A ni ti Adam ati Efa, ti işẹdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa nina ọla rẹ, ati nigbati o di ẹranko; ti obirin ti o fi ọwọ mu ejo, ati ti Ọba Tatambulu.

A ni ewe Taba fun kika ta, Ọşẹ Olọwọ—agaga; Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ wa fun tita bi wọbu, bi o ba fẹ ẹ ni *lọnu* a le ta a fun o, Işana Alapoti fun tita, ko si bi a ti nşe wọn. Orişirişi ọja lo wa lọwọ wa, iwọ ko le ba wa şowo ko ma jere lirẹ, nitori owo pọku ni a nta wọn. Owo ọja wa rọju rekọja ala. Bi o ba wa si ile-ọja wa "Ka mi, ka mi, ka mi" ni gbogbo won, bi o ba fẹ ja irọ wa, rin wa si ile ọja wa.

Iye owo wọn:—3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan; 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ẹhin okun kọwe şowọ yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba si:—

E. O. AMBẸ & BROS.
38, Moloney Bridge Street, Lagos.
(*Ẹgbẹ awọn Onişowo A. J. Tangalakis*).
Idumagbo, Eko.

*Ibi ni ẹnyin ro si mi—Şugbọn Oluwa mọ si rere.*

OKANLAWON BALOGUN BROTHERS

Dealers in best quality of Produce viz:—Cocoa, Kernels, Palm Oil, Skins of any kind etc., etc., etc.

*Head Office*:—16, BANKOLE STREET, LAGOS.

*Branches at*:—Lagos, Agege, Agbado, Ifo, Ilori, Wasinmi, Owowo, Ibara, Lafenwa, Ibadan, Ileigbo, Iwo, Ikirun and Oshogbo.

*A trial order will be thankfully solicited.*


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.